# AWỌN ASỌTẸLẸ ISAIAH NIPA KRISTI ATI IMUṢẸ WỌN

**Isaiah 7:14; 9:1-7; 11:1-5; 42:1-4; 53:1-12**

**ẸKỌ 364 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika rẹ̀: a o si ma pe orukọ rẹ̀ ni Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia" (Isaiah 9:6).**

**I Ibi Iyanu Ti Kristi**

1 Ọlọrun ṣeleri igbala fun Ọba Ahasi, a fi àmì kan fun un ti i ṣe asọtẹlẹ ti igbala gbogbo agbaye, Isaiah 7:1-14; 52:10

2 A ti ipasẹ wundia kan bi Jesu, eyi si mu ọrọ nipa àmi naa ṣẹ, Matteu 1:18-25

**II Ileri Imọlẹ Nla Kan**

1 Awọn eniyan ilu Sebuloni ati Naftali yoo ri imọlẹ nla kan, Isaiah 9:1-5; Matteu 4:12-16; Luku 2:32

2 Jesu ni Imọlẹ ayé, Johannu 1:4-10; 8:12

**III Iṣẹ-iranṣẹ ati Ijiya Kristi**

1 Oun jẹ́ ọlọkan-tutu ati oninuure ninu iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀, Isaiah 42:1-4; Matteu 12:15-21; Johannu 12:37-41

2 Isaiah sọ asọye nipa ti ijiya Kristi, Isaiah 53:1-12; Iṣe Awọn Apọsteli 8:32-35; 1 Peteru 2:23, 24

**IV Ọba ti O N Bọwa**

1 Ijọba yoo wa ni ejika Rẹ̀, Isaiah 9:6, 7; 11:1-5; Ifihan 19:11-21; 20:1-5

## ALAYE

### Ami Kan

Awọn asọtẹlẹ Isaiah nipa Kristi pọ pupọ; wọn bẹrẹ lati igba ibi Rẹ̀, iṣẹ-iranṣẹ Rẹ, ijiya Rẹ, ikú ati Ijọba Ẹgbẹrun Ọdún Rẹ̀. Ni akoko kan, nigba ti Ahasi Ọba Juda, kún fun ibẹru nitori pe Siria ati Israẹli dimọ pọ̀ si ile Dafidi, Ọlọrun rán wolii Rẹ̀ Isaiah si i lati mu ki o da a loju pe Juda yoo ni Olugbala kan. Ọlọrun sọ fun Ahasi pe ki o beere "ami kan lọwọ OLUWA Ọlọrun rẹ; bere rẹ́, ibã jẹ ni ọgbun tabi li okè," ṣugbọn Ahasi pẹlu ẹmi ibọwọ fun Ọlọrun, kò jẹ beere. Nigba naa ni Oluwa sọ fun ile Dafidi pe: "Nitorina, Oluwa tikalarẹ̀ yio fun nyin li àmi kan, Kiyesi i, Wundia kan yio loyun, yio si bi ọmọkunrin kan, yio si pe orukọ rẹ̀ ni Immanuẹli" (Isaiah 7;14). Eyi ni iṣẹ-iyanu ti yoo ṣẹlẹ, ti yoo jẹ́ àmi fun igbala Juda.

### Ibi Iyanu

O lé ni ẹẹdẹgbẹrin (700) ọdún ki àmi naa to ṣẹ, ṣugbọn ni ọjọ kan a ri wundia kan "o lóyun lati ọwọ́ Ẹmi Mimọ́ wá" (Matteu 1:18). Josẹfu ẹni ti a fẹẹ fun, n fẹ kọ Maria silẹ ṣugbọn angẹli fara hàn an, o si wi fun un pe: "Josẹfu, iwọ ọmọ Dafidi, má fòiya lati mu Maria aya rẹ si ọdọ; nitori eyi ti o yún ninu rẹ̀, lati ọwọ́ Ẹmi-Mimọ́ ni. Yio si bi ọmọkunrin kan, JESU ni iwọ o pè orukọ rẹ: nitori on ni yio gba awọn enia rẹ̀ là kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn" (Matteu 1:20, 21).

"Gbogbo eyi si ṣẹ, ki eyi ti a ti sọ lati ọdọ Oluwa wá li ẹnu woli ki o le ṣẹ" (Matteu 1:22). Bi o tilẹ ṣe pe a ni akọsilẹ ti o ye kooro nipa ibi Jesu lọna iyanu, iṣẹ ti angẹli jẹ́, ami ti wolii ṣeleri rẹ̀ ati ọ̀rọ ti Apọsteli naa sọ gẹgẹ bi a ti kọ ọ silẹ, sibẹ awọn alafẹnujẹ aṣiwaju Igbagbọ́ lode oni n sẹ́ iwa Ọlọrun Kristi ati ibi Rẹ̀ lati inu wundia. Wọn gba A si eniyan kan ṣá. Awọn olukọ igbalode wọnyii ti lọ jinna to bẹẹ ti wọn yi Ọrọ Bibeli pada si eyi ti a n pe ni Revised Standard Version ninu eyi ti wọn lo "ọdọmọbinrin" dipo "Wundia" ninu asọtẹlẹ Isaiah. Ninu eyi ati ọ̀pọlọpọ ibomiran ni wọn ti lo ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ lati ta abuku si iwa Ọlọrun Kristi. Ṣugbọn otitọ naa duro lai le yi pada: Ọmọ Ọlọrun ni Jesu I ṣe; ami ti a si fi fun ni nipasẹ Wolii Isaiah ti ṣẹ -- a bi Olugbala nla naa nipasẹ wundia kan.

### Imọlẹ Nla Naa

Ipinlẹ Sebuloni ati ipinlẹ Naftali jẹ eyi ti ogun ti fọ́, ti ọ̀pọ awọn keferi si ti sọ di ahoro; awọn eniyan ibẹ kò ni iru ọlaju ti awọn ti iha gusu ilẹ Palẹstini ni, ṣugbọn a maa n wò wọn bi alailẹkọọ ati ẹlẹṣẹ. A maa n ṣe apejuwe agbegbe wọn bi ilẹ "okùnkun" ati "ipínlẹ ojiji ikù." Si adugbo yii, "Galili awọn keferi, ni Ẹni naa ti wá, ẹni ti a bi ti i ṣe Ọba awọn Ju, ẹni ti Isaiah pe orukọ rẹ ni "Iyanu, Oludamọ̀ran, Ọlọrun Alagbara, Baba Aiyeraiye, Ọmọ-Alade Alafia" (Isaiah 9:6).

Ileri didun naa wá si ọdọ awọn ti igbesi-ayé ailofin ati isọ-di-ahoro-ogun ti mọ́ lara: "Ijọba yio bi si i, alafia ki yio ni ipẹkun: lori itẹ Dafidi, ati lori ijọba rẹ̀; lati ma tọ́ ọ, ati lati fi idi rẹ̀ mulẹ, nipa idajọ, ati ododo lati isisiyi lọ ani titi lai" (Isaiah 9:7). Iru itànṣán imọlẹ wo ni yii! Iru ireti ologo wo ni yii fun awọn eniyan ti wọn ti di atẹmọlẹ! Imọlẹ nla naa ti tàn si wọn. Si ẹsun awọn akọwe ati awọn Farisi ti wọn da A lẹbi fun fifi ara-rora pẹlu awọn ẹlẹṣẹ, Jesu dahun pe, "Emi kò wá ipe awọn olododo, bikoṣe awọn ẹlẹṣẹ si ironupiwada" (Luku 5:32). Simeoni sọ nipa Jesu gẹgẹ bi "imọlẹ lati mọ́ si awọn Keferi, ati ogo Israẹli enia rẹ" (Luku 2:32).

**Okunkun**

"Ninu rẹ ni iye wà; iye na si ni imọlẹ araiye. Imọlẹ na si nmọlẹ ninu òkunkun, òkunkun na kò si bori rẹ̀" (Johannu 1:4, 5). Imọlẹ nla naa ti o tàn si òkunkun Naftali ni "Imọlẹ araiye." Ṣugbọn ayé kò fẹ gba A; oye Ijọba Rẹ̀ kò yé wọn. "Awa gbọ́ ninu ofin pe, Kristi wà titi lailai: Iwọ ha ṣe wipe, A kò le ṣaima gbé Ọmọ-enia soke?" (Johannu 12:34). "Nitorina nigbati ọ̀pọ ninu ijọ enia gbọ́ ọrọ wọnyi, nwọn wipe, Lotọ eyi ni woli na. Awọn miran wipe, Eyi ni Kristi na. Ṣugbọn awọn kan wipe, Kinla, Kristi yio ha ti Galili wá bi? Iwe-mimọ́ kò ha wipe, Kristi yio ti inu irú-ọmọ Dafidi wá, ati Bẹtlẹhẹmu, ilu ti Dafidi ti wa" (Johannu 7:40-42).

Lati inu ọrọ awọn eniyan wọnyii a ri i pe wọn ni oye apa kan Iwe Mimọ́ -- wi pe Ijọba rẹ̀ yoo wà titi, wi pe Oun ni. "Ẽkàn lati inu kùkute Jesse," ṣugbọn wọn kò mọ̀ pe a ni lati "pa a li ara nitori aiṣedede wa" (Isaiah 53:5). Ni igba miiran wọn n fẹ fi I jẹ ọba, oye kò si ye wọn nigba ti O "kilọ fun wọn pe, ki nwọn ki o máṣe fi on hàn" (Matteu 12:16), bi o tilẹ jẹ pe Isaiah ti wi pe "On ki yio kigbe, bẹ̃ni ki yio gbé ohùn soke, bẹ̃ni ki yio jẹ ki a gbọ́ ohùn rẹ̀ ni igboro" (Isaiah 42:2).

**"Ọdọ-Agutan fun Pipa"**

Lotitọ, Jesu ni Ẹni naa ti Isaiah sọ nipa Rẹ nigba ti o wi pe "Nitori a bi ọmọ kan fun wa, a fi ọmọkunrin kan fun wa: ijọba yio si wà li ejika rẹ" ṣugbọn oye kò ye awọn eniyan pe ìbí Rẹ gẹgẹ bi eniyan jẹ apa kan ninu wiwá Rẹ̀. Wọn kò mọ̀ pe wíwá Rẹ̀ ni igba ekinni gbọdọ jẹ́ "gẹgẹ bi ọdọ-agutan fun pipa," gẹgẹ bi "ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ" (Isaiah 53:7, 10). Sibẹ Isaiah ti sọ fun wọn nipa ijiya Kristi ati ibanujẹ Rẹ̀.

Ọ̀kan ninu awọn asọtẹlẹ kikun ti Isaiah fun ni ni pe: "O si ṣe iboji rẹ̀ pẹlu awọn enia buburu, ati pẹlu ọlọrọ̀ ni ikú rẹ̀" (Isaiah 53:9). A mu eyi yii ṣẹ nigba ti a kan Jesu mọ́ agbelebu laaarin awọn ole meji – "a kà a mọ awọn alarekọja" (Isaiah 53:12) – ati nigba ti Josẹfu ọlọrọ ara Arimatea, tẹ́ oku Jesu si iboji oun tikara rẹ̀.

**Ọmọ-Alade Alaafia**

Awọn asọtẹlẹ Isaiah nipa Kristi kò pari si iboji, ṣugbọn o lọ siwaju titi di ọjọ nì nigba ti "yio fi ododo ṣe idajọ talaka, yio si fi otitọṣe idajọ fun awọn ọlọkàn tutu aiye; on o si fi ọgọ ẹnu rẹ̀ lu aiye, on o si fi ẽmi ète rẹ̀ lu awọn enia buburu pa" (Isaiah 11:4). A mu ki o da ni loju ninu Iwe Ifihan wi pe eyi ṣi n bọ̀ wá ṣẹ. "Ninu ododo li o nṣe idajọ, ti o si njagun. … Ati lati ẹnu rẹ̀ ni ida mimu ti njade lọ, ki o le mã fi iṣá awọn orilẹ-ède: on o si mã fi ọpa irin ṣe akoso wọn" (Ifihan 19:11-15). Lori itẹ Dafidi ni Ẹni kan yoo joko ti yoo "fi idi rẹ̀ mulẹ, nipa idajọ, ati ododo lati isisiyi lọ, ani titi lai" (Isaiah 9:7). Lẹyin pipa awọn eniyan buburu pẹlu idà ti o jade lati ẹnu rẹ̀ (Ifihan 19:15, 21). Ọmọ-Alade Alaafia yoo gba ijọba si ejika Rẹ̀ yoo si bẹrẹ ijọba alaafia ti ẹgbẹrun ọdún ti o ni ibukun (Ifihan 20:1-6), pẹlu awọn ti n fẹ rin ninu imọlẹ. "Ayọ̀ li ẹ o fi jade, alafia li a o fi tọ́ nyin: awọn oke-nla ati awọn oke kékèké yio bú si orin niwaju yin, gbogbo igi igbẹ yio si ṣapẹ́" (Isaiah 55:12).

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ami ti Oluwa fun ni gẹgẹ bi idaniloju igbala Rẹ̀ fun awọn eniyan Rẹ̀?
2. Darukọ diẹ ninu awọn orukọ ti a fun Kristi.
3. Nibo ni ipinlẹ Sebuloni ati ti Naftali wà?
4. Nigba wo ni Imọlẹ nla naa mọ́ si wọn?
5. Nigba wo ni Jesu yoo fi eemi ẹnu Rẹ̀ pa awọn eniyan buburu?
6. Nigba wo ni Jesu yoo joko lori itẹ Dafidi?
7. Awọn diẹ wo ninu awọn gbolohun ọ̀rọ ti o wà ninu Isaiah 53 ni n tọka si Ẹjẹ Etutu Jesu?
8. Sọ diẹ ninu awọn asọtẹlẹ kikún nipa ijiya Kristi ati imuṣẹ wọn.